# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL "XIV" 855 LAGOS SATURDAY FERUARY 2nd — FEBRUARY 8th 1963 KOBO MEJI (2D.)

### Enkuari Miran De!

## Nwon Fe Mo Nkan Ti O Pa Olympio Ni Ilu Togo

COTONON (Dahomey)—Nwọn agbajọ ọwọ n i a fi sọ aya; gbogbo awọn aṣoju orilẹ ede ilu Afrika marun ti apejọ awọn ogunnagbogbo yan nn ipade nla? kan ti nwọn ṣe l'Eko ni ọsẹ t i o kọja, ti bẹrẹs pẹjọ si ilu Cotonon loru ana lati bẹrẹsi ṣe iwadi bawọ ni alamojuro Ijọba ilu TOGO ti nwọn npe orukọ rẹ ni Dokita Sylvanus Olympio se ku lọwọ a w ọ n ọlọtẹ ilu na ti o yinbọn pa a.

Awọn orilẹ-ede ilu ti apejọ awọn ogunna gbogbo na yan wipe ki nwọn ṣ e i w a d i (ẹnkuari) na jẹ marun, awọn n a ni Nigeria, Dahomey, Ivory Coast, Upper Volta ati awọn orilẹ ede ti a npe ni Niger. Dokita Emil Zinsou, Minisita alamojuto nkan okere ni ilu Dahomey ni yio ṣe iwadi na, Ọgbẹni M. T. Mbu, Minisita alamojuto eto awọn ọmọ ogun oju omi ni ijọba ilu Nigeria ran lọ gẹgẹbi aṣoju wọn, O si si ti lọ si Cotonu nibiti nwọn ti bẹrẹ iṣẹ iwadi ni ana.

Lẹhin eyi gbogbo awọn aṣoju ti nwọn nṣe iwadi na yio fi lọ fi ijoko iwadi wọn si Lome ni ilu awọn ara Togo ni ọtunla Monday nibiti iṣẹlẹ na ti sẹ ti awọn ọlọtẹ gbe pa Dokita Olympio.

Gbogbo awọn ilu agbaiye ni o ni awọn fẹ mọ bi iku ile ni tabi tode ni o pa alamojuto ilu Togo na.

### Moto Pa Malu:

## Alapata F'owo Gbag Nilu Oyinbo

READING—Ẹjọ pataki kan ti adajọ-agba kan ti oru kọ rẹ nje Claude Duveen da ni ilu Oyinbo f u n awọn ẹgbẹ Alapata ẹran ni ana ti a ri wipe a w ọ n alapata tabi awọn oni malu ti o nda malu ni ile wa le ri ọgbọn kọ nibẹ ni ti awọn ẹgbẹ alapata ti orukọ wọn njẹ Phillmore Estates Limited ti nwọn ni awọn fẹ gba pọnun mẹtalelogoje lọwọ baba onimọto. Ọgbẹni Ernest Parry ti o fi mọto rẹ kọlu malu awọn loju ọna nigbati awọn nda wọn lọ loru ọjọ kan.

Adajọ na kọ lati fọwọ si iwe pe ki onimọto na san owo yi fun awọn alapata na. O ni awọn lo jẹbi nitoripe nwọn ni lati tan ina si atupa niwaju a t i lẹhin nigbakugba ti nwọn ba nda ẹran wọn lọ loru.

Adajọ na si ki awọn alapata yi lọ san adọsan pọnun (£170) fun baba onimọto na fun moto-ayọkẹlẹ rẹ ti nwọn bajẹ.

### LAGOS RACE CLUB

**Spring Meeting, 1963.**

SATURDAYS 16TH, 23RD FEBRUARY 2ND & 9TH MARCH 1963.

Provisional Progamme and Entry Forms can be obtained on application to the Secretary, P. O. Box 51, Lagos or at the Race Course, Lagos.

Note-No Entry fees will be refunded after the draw has been made.

Entries close at noon on Tuesday 5th February, 1963.

No Cheque will be accepted.

C. H. E. MILLER
Hon. Secretary.

## IROHIN SOKI

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

### Minisifa Eko

Mo gbọ irohin wipe Alhaji A. F. Masha tiṣe a l a g a Igbimọ tuntun ti Minisifa Eko (Lagos Town Council) lọ fi "oju agba" kan Ọlọla Alhaji Tafawa Balewa, alakoso Ijọba Apapọṣe l'Eko ni ọjọ Ọjọbọ (Alamisi) ijẹta ni ibi iṣẹ rẹ, nwọn si sọrọ pupọ nipa ilọsiwaju fun awọn ara ilu Eko.

Mo gbọ wipe kiki ti alaga tuntun Minisifa wa ki Ọlọla Tafawa wa yi dun mọ pupọ tobẹgẹ ti o fi bẹrẹsi baa sọ ọrọ ifẹ wipe a dun mọ on bi awọn aṣoju igbimọ tuntun na ba nle ṣe iṣẹ wọn laisi isaju nibẹ. Ọlọla Tafawa ni alafia ati nkan rere ni on fẹ fun awọn ara Eko, ko ba nṣe Yoruba, Gambari tabi Ibo. Ti nwọn ba ti nṣe ẹtọ fun awọn ara ilu, on ti ṣe tan lati ran wọn lọwọ nibiti ọrọ ba di koko fun wọn.

### Owo Lo Tan

Mo gbọ wipe ọrọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ni nwọn sọ ni apejọ awọn Minisifa Eto owo ti gbogbo awọn Minisifa Ipinlẹ mẹrẹrin wa ṣe l'Eko nini ọsẹ yi.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

## Opolopo Ile Iwe Ni Nwon Ti Nilu Ibo

ẸNUGU—O to iranwo ile-iwe ti a w ọ n alamojuto eto ẹkọ ni ipinlẹ Ila Orun ni ilu awọn Ibo; n i k i nwọn ti patapata nitoripe opolopo awọn ile ẹkọ na ni nwon ko yanju to bi awọn ti fẹ.

A gbọ wipe ọran ile-iwe titi yi fẹ da nkan silẹ larin awọn ara Ipinlẹ na nitoripe ogunlọgọ awọn ọmọde ni ọrọ titi ile iwe na kan pẹlu tiṣa wọn.

Onirohin wa lati Ẹnugu ni awọn Ijọ C. M. S. ni Onisha ti nwọn ni ki nwọn ko ti ile-iwe alabidi ti o wa labẹ wọn ti fi aake kọri pe bi o ba ti g b a n i awọn yio ṣee, awọn ko ni ti awọn ile-iwe ti wọn.

Akọwe ti o wa fun eto ẹkọ ti ijọ Ṣọsi na, Ọgbẹni E.O. Enemo ni g b o g b o nkan ti Ijọba Ipinlẹ I l a Orun nfẹ nipa ile iwe ti o yanju ni awọn ti ṣe; o ju ọgọrun awọn olukọ t i ko ti mọ iṣẹ daradara t i awọn tilẹ ti da duro lẹnu iṣẹ tiṣa nisisiyi.

## A won Onisowo Kan Lu Olowo'ri Loja

ONITSHA — I j ọ buruku eṣu ko bomi w ẹ ni ijẹta jẹ fun awọn akọwe olowo-ori Ijọba nigbati nwọn lọ si ọja lati lọ yẹ iwe awọn t i nwọn b a ti gba owo ori wo ati awọn ti ko ti gba rara ki nwọn ba le mọ ọna ti nwọn yio gba ki owo le wọ apo Ijọba.

Gbara ti awọn onisowo ti o wa lọja yi ti fi oju kan awọn akọwe olowo-ori na pẹlu moto w ọ n, igi ati Kumọ n i nwọn yọ si wọn, nwọn si lu wọn nilukulu. Gbogbo moto wọn ni wọn ba jẹ.

Nigbati ariwo ija na lẹ tan kakiri gbogbo ọja ni awọn kan ba lọ pe awọn ọlọpa wa. Awọn enia ti ọwọ awọn ọlọpa ba le ni adọrin lọjọ na. Awọn ọlọpa si nṣe iwadi ki lo fa sababi ọrọ na lọwọ.

Ọgbẹni J.C. Amago tiṣe ọga awọn olowo-ori ti fun awọn enia rẹ laṣẹ wipe ki nwọn ma ko ẹru awọn ti ko san owo-ori fun t i t a ni gbanjo.

## Awon Olopa'nu Ye Ile Tisa Aluko Wo

IBADAN—A gbọ ya'nu ni ọrọ na jẹ fun a w ọ n ọmọ ilewe gigajulo ti a npe ni University ni Ibadan nigbati nwọn ri awọn ọlọpa'nu ti nwọn g b e moto ati iwe-aṣẹ wa sinu i l e ọkan ninu awọn o l u k ọ wọn ti nwọn npe ni Dokita S A Aluko lati wa tu yara rẹ wo boya awọn le iwe ti o lodi sofin nibẹ.

Gbogbo iyẹwu ti o wa ni inu ile olukọni n a n i awon ọlọpa na yẹ wo kinni--kinni, nwọn si ri awọn iwe meji tabi mẹta kan ko lọ.

Ẹrin ni Dokita Aluko alara paapa nfi wọn rin. O ni ọrọ otitọ ti on kọ sinu iwe irohin n i p a ẹjọ apakan ti nwọn da nipa ọrọ ẹnkuari (iwadi) ti Adajọ Coker ṣe ni o nta awọn alamojuto Ijọba lara ti nwọn nṣe fi ara lugi lu ọpẹ kakiri.

Awọn ọlọpa si nro ọrọ iwe ti n w ọ n ri k o lọdọ Dokita Aluko lọwọ.

# Awon Olosa Di Olopa Ni Ona Onitsha

Onitsha—Ọrọ bẹhin yọ! awọn ọlọṣa kan di ọlọpa ninu igbo lọna Onitsha laipẹ yi nwọn si bẹrẹsi ko ẹru elẹru ninu mọto nibiti nwọn gbe ba si loru ọganjọ pẹlu ibọn lọwọ wọn.

Onirohin wa ni l ọ j ọ ti nkan yi yio ṣẹlẹ a w ọ n onisowo k a n mu mọto-akẹru lati ilu Oweri w a si ọja Onitsha lati w a ra orisisi asọ a t i awọn nkan miran, nwọn si di ẹru wọn sinu mọto na o kun bamubamu.

Nigbati o di o r u ọganjọ ninwọn ba mu ọna pọn ni nwọn gbe m ọ t o na pẹlu awọn ẹru inu rẹ lati pada si Owerri. Nwọn ko rin jinna pupọ ninu igbo ki nwọn to pade a w ọ n ọkunrin kan ti o wọ a s ọ ọlọpa a-mu-mọto (traffic police) lati oke de'lẹ nwọn ni ki nwọn d a mọto wọn duro ki awọn y ẹ iwewọn wo.

Nibiti nwọn gbe nyẹ iwe dẹrẹba onimọto ea wo lọwọ ni awọn ẹmẹwa wọn yoku jade ninu igbo pẹlu i b ọ n lọwọ, nwọn le gbogbo awọn ero inu moto na jade, nwọn si gba gba gbogbo owo ọwọ wọn, nwọn si wa m ọ t o-akẹru na gba ọna Okiwi lọ.

Awọn ọtẹmuyẹn ọlọpa'nu si nṣe iwadi ọrọ ọlọpa ti o di ọlọṣa na lọwọ.


**HAVE YOU SEEN THE NEW MODEL "SLIMSTYLE"?**

- LAMBRETTA 3RD SERIES
- THE SCOOTER WITH TRADITION
- NEW SLEEK ELEGANT LINES
- SAFETY - **DISK BRAKES**
- ECONOMY - 120 m.p.g.



**Lambretta**

**Leventis Motors Ltd.**

Lagos . Ibadan . Kano . Kaduna . Jos . P. Hacourt . Aba

# Bawo Ni Olympio Se Ku Lori Oro Ilu Togo....?

Egbe Odo

Gẹgẹbi mo ti sọ fun yin ninu iwe itan mi iṣẹ ti o kọja wipe ko si ẹnikan ṣoṣọ ti o fi idibo wọle Igbimọ aṣofin ilu Togo ninu awọn ọmọ ẹgbẹ JUVENTO ati ẹgbẹ oṣelu ti Ọgbẹni Nicholas Grunitsky (ti o di alakoso Ijọba nisisiyi) da sile, ti o sọ ni Ẹgbẹ DEMỌ ilu Togo (Democratic Union of Togolese Peoples) nigbati awọn ara ilu na dibo ni ọdun keji sẹhin. Mo ro wipe ki a ma ṣe ani-ani enyin na ti wa mọ diẹ ninu bawo ni ọrọ wọnọṣelu ilu Togo na ṣe bẹrẹ nisisiyi. Eleyi a si le jẹ ki ẹ le ma fi ọkan gbe iwadi pataki ti emi OLOFINTOTO ṣe lori ọrọ awọn oṣelu Togo.

Nkan ti o ba wọn awọn ọmọ egbe-ọdọ lọjọ idibo na lọhun) ni ti iwe idibo wọn ti awọn ẹgbẹ mejeji Juvento ati Dẹmọ dapọ lati fi orukọ awọn si awọn baba eleto idibo; nwọn ni eyi ko tọna rara gẹgẹbi ofin ilu na orukọ gbogbo awọn ọmọẹgbẹwọn na ni ojona bamubamu

## "Ayegbe"

Lati igba na lọ awọn ọmọ ẹgbẹ na ko sun, nwọn ko si wo lori ọrọ ilu Togo. Dokita Olympio paapa ri wipe iwa awọn ọmọ ẹgbẹ na ngbona mọ Ijọba on iara, o paṣẹ kakiri wipe ki nwọn ye ṣe ẹgbẹ oṣelu na mọ ni ilu

Togo nwọn si fi ofin ko awọn diẹ ti o jẹ olori ninu awọn ọmọ ẹgbẹ na lọ fi pamọ si ọgba ẹwọn.



Olympio

Awọn miran ninu awọn ogunna gbogbo ọmọ ẹgbẹ na sa lọ fi ara pamọ si ilu Dahọmi (Dahomey) ti ko jinna si wọn, awọn kan si gba Ghana lọ lati lọ fi ori si abẹ abo alamojuto Ijọba Aganyin, Dokita Nkrumah.

Telẹtelẹ ọkansoso ni ilu Togo ri labẹ awọn Oyinbo Jamani ki ogun agbaiye to de ni ọdun 1914. Ninu

LATI ỌWỌ OLOFINTOTO

ogun yi awọn Oyinbo alagbara meji, Gẹsi ati Faranṣe ni awọn gbe ogun ti awọn Oyinbo Jamani (Germans) ti nwọn wa nibẹ, awọn mejeji na si bori wọn. Eleyi mu awọn Ijọba agbaiye (League of Nations) da ilu Togo na sọna meji, nwọn ko apakan fun awọn Gẹsi, apa keji fun awọn Faranse ki nwọn ma jọba lori wọn.

## EDe Ewe

Awọn ijọba Oyinbo mejeji yi jẹba lori ilu yi titi ki nwọn to fun ilu na ni ominira ni iwọn ọdun meji sẹhin. Ṣaju eleyi ni alamojuto Ijọba ilu Aganyin; Dokita Nkurumah, ti nsọ ọ mọ ọrọ wipe nkan elo ni ilu Togo fun on, on si fẹ ki nwọn da ilu na mọ Ghana ki awọn jọ ma ṣe pọ.

Awọn kan ninu awọn ara ilu na faramọ ki nwọn da a mọ ilu Ghana, awọn kan lodi si eto aladapọ yi. Awọn ẹgbẹ-ọdọ ti nwọn nje Juvento Party ninwọn faramọ eto ki nwọn ba Ghana lọ, sugbọn awọn ẹgbẹ Dokita Olympio ko jalẹ; nwọn ni ki olukuluku ṣe tirẹ lọtọtọ.

Ọrọ yi ko dun mọ awọn ara ilu Ghana ninu rara, paapa alamojuto Ijọba ilu Ghana Dokita Nkumah, ti o ti fọkan si i wipe iru adapọ bayi a jẹki ilu on tobi diẹ si, a ye a si wa fun awọn ọmọ ilu on lati ribi na'pa na'sẹ si.

"Ayegbe" ni awọn ara Ghana npe awọn ọmọ ilu Togo ti nwọn nṣe iṣẹ ni ilu Ghana; nwọn si po jaburata nibe ti nwọn nṣe iṣẹ owo kiṣe lọkunrin ati lobinrin.

## Olorida

Dokita Nkrumah, alamojuto Ijọba Ghana fi igba kan sọ wipe ilu on jo ni ilu ti awọn npe ni Togo, awọn Oyinbo ajoji ni nwọn gba a lọwọ awọn nigba kan ṣugbọn on ni lati ri wipe on gba ilu na pada sọdọ awọn ara Ghana ti nwọn ti gba ominira wọn lọwọ awọn Faranse.

Ẹnu Dokita Nkrumah yi nfọnti mbẹ ọpọ awọn agbalagba ara ilu Togo ti nwọn mọ ibi ọrọ na gbe le yọn si ninu. Nitori ilu Ghana pẹlu Togo jọ pa ala pọ nwọn ko si jinna si ara wọn bi ilu DAHOMI.

Lati igbati ilu Togo ti gba Ominira ṣe lọwọ awọn Faranse ni awọn ara ilu Aganyin ni Ghana ko ti ba wọn ṣ ọrẹ deede to bi mọ lori ija nipa ala ti o wa larin wọn. Ọrọ ala-ilẹ na fẹ bi'ge b'adabi ni arin awọn ara oke ilu wọn ni Upper Volta.

## Oko Aje ilu Oyinbo



**Aworan yi ni ti awon wundia marun omo Oyinbo ninu oko-aje kan ti nwon gbe jade laipe yi nibiti nwon gbe se ere ifi aso tuntun han ni Earls Court London. Gbogbo awon orile-ede ti o ko awon oja ilu won wa si ibi eto ifihan lati wa fi ase ilu won han le ni meiila awon asoju won paapa je edigbe... ti nwon ko oru...**

# ELEI – OFE

ANJUWON KO SE WI LEIO

EDITORIAL OFFICE & WORKS 28, Kosoko Street, Lagos. P. O. Box 468

CABLES & TELEGRAM "ELETI–OFE" LAGOS Phone 23370

VOL XIV No. 556 SATURDAY FEB. 2, – FEB. 8 1963


# Iwe Enia Ti a Ka Da ?

Nwọn ni bi ina ko tan laso eje ko ni tan ninu ekanna. Nkan ti o mu wa pa owe bayi ni iwe kan ti a ri gba lati ọdọ ọkawe wa kan ni ilu awọn Ajaṣẹ (Coutonu) ti o mbere pe bawo ni nwọn ti yanju awọn enia ti nwọn ka kakiri gbogbo ilẹ Nigeria si, tabi nwọn ko fẹ gbe ọrọ enia kika na sode ni.

## Amodi Ni Ile

Nwọn ni bi a ba nsọkun a ma riran ; ọrọ enia kika na ti to nkan ti a ni lati gbe iyọri rẹ si ita gbangba ti gbogbo ara ye ni lati mọ iye nkan ti awọn Ijọba ka wa si.

Ara ile eni ni mọ ọ ni amodi• arunn ni ara ita pe e. Bi ọrọ iyọri enia kika na ti nwọn ko gbe jade ti ru awa oniwe irohin Eleti – Qfẹ loju a si ṣe akiyesi pe ọrọ na ti su awọn ara ita paapa.

## Arun Nita

Bi ko ba jẹ wipe a fẹ ṣe mukaru nidi ọrọ na o yẹ ki nwọn gbe iwe eto enia kika na jade.

Bi awọn alamojuto Ijọba apapọṣe wa ko ba mọ wipe nṣe ni a nṣe nkan ni aṣepe ki a kuro nibẹ, awọn ajoji lati ilu okere wa ni o nsọ fun wọn yi.

Nitotọ arun ni ara ita npe e, ara ile ni mọọ ni amodi.

## Baba Elere



Aworan yi ni ti Ogbeni Paul Daneman, baba elere kan ni ilu Oyinbo ti gbogbo awon enia mo ile ere won ni Nittingham Play Company ti nwon si nrin irin–ajo kakiri ile enia dudu nisisiyi pelu awon omo elere re

# Iwe Si Olotu

## Awon Tisa Opuro

Ẹ jọwọ ẹ gba mi laye ninu iwe irohin lati kin Olotu Eleti–Qfẹ lẹhin fun ọrọ ti o sọ laipẹ yi wipe ọpọlọpọ awọn tisa olukọni ni o ti ba aiye awọn ọmọ ti nwọn nkọ lẹkọ jẹ nipa aisọto wọn.

Mo kan sara fun Olotu na lori ọrọ rẹ na NITOTỌ ko si ọjọ kan ti a o gbe iwe irohin ti a ko ni irohin ka wipe akọwe kan ti owo awọn ọga ti o mba sisẹ gbe, nwọn si ju u sẹwọn,

Ni aiye atijọ iyekiye ti nwọn ba nsan fun awọn akọwe tẹ wọn lọrun, ninu rẹ na a gbe iyawo a kọle, a si gbọ t'ẹbi nibẹ.

Ni aiye isisiyi ọkanjuwa ti gba ọkan awọn ọdọmọde wa, gbogbo wọn ni nwọn fẹ ra moto ayọkẹlẹ. Qrọ na wa d'ọwọ awọn obi wọn.

Ẹ ṣe pupọ ti ẹ nṣi wa leti.

Emi ni
Bamidele

Suru-Lere
Yaba

## Kilo Fa Awe ?

Ẹ jọwọ ẹ gba mi laiye lati bere ibere kekere kan lọwọ awọn ẹgbẹ mi Musulumi. Mo ki awọn ẹlẹgbẹ mi na gbogbo ti ẹ j; Musulumi pe wọn ku ọdun, nwọn ku iyedun.

Ẹnyin Musulumi mo fẹ mọ idi re ti a fi nkirun. Mo fẹ mọ idi ti a fi ngba-

Awẹ. Awọn ẹlomiran ma mbere lọwọ ẹnikeji wipe kini de ti iwọ ko gba awẹ. Ṣe o ni ẹtọ lati bere ni ?.

Mo fẹ ri esi ibere mi yi ninu Iwe Eleti-Qfẹ. Ibi ti nwọn wa niyi : -

ELETI–QFẸ.
28, Kọsọkọ St. Lagos.

Emi ni

Eko.     Tajudini Eweina.

## Enia Kika Da . .?

Kiloṣe ti a ko tun gbọ irohin kan mọ nipa awọn enia ti nwọn ka ni Nigeria ninu ọdun ti o kọja tabi iyọri enia kika na ko ṣe gbe jade ni?

Awa ti a ba Yoruba tan ti a wa ni Kontonu (Coutonu Dahomey) fẹ mọ idi bi ọrọ enia kika na ti pari si.

A nfi oni dọ'la kole yanju ọrọ na ; tabi Ijọba Nigeria l'Eko ko fẹ ṣe ẹtọ lori ọrọ enia kika na in.

Emi ni,

Muritalabi,

Coutonu,—
Dahomey.

## Oje Ope Dara Pupo

Mo gbọ wipe awọn ọlọgbọn kan ni ilu Oyinbo ti fake kọ wipe awọn ni lati wo idi bi igi ọpẹ (palm tree) ṣe nilati mo hu ni ilu awọn nitori nkan rere ti o nṣe ọmọ enia pọ lara igi na.

Mo gbọ wipe epo pupa ti awọn Oyinbo nra lowo iyebiye lọwọ wa, oriṣiriṣi nkan egbogi ni nwọn nfi ṣe pelu ekuro ti a nri lara ọpẹ.

Mo tun gbọ wipe awọn ọjọgbọn kan ti fi ọkọ ofurufu ru ẹmu lọ si ilu Oyinbo fun iwadi atata. Kiloṣe ti awa na kole ṣe iwadi lati mọ ọna rere ti a le ma lo oje ti a nri lara igi ọpẹ wa si?

Ẹnyin ọjọgbọn wa ọrọ re o!

Emi ni,

Amos Amọo

Ibadan

# E ma Ka Iwe Irohin Eleti—Ofe Fun Irohin Aladun losose

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

## Iku Do-ro

Iku doro pupọ! Ninu oṣu ti o pari yi awọn enia oninure mẹta ni mo mọ ti iku gba lọwọ wa laburadi, Ikinni ni ọmọdekunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Sigismund Babatunde Joseph ("BAJOS") ti o jalaisi ninu ile rẹ ni Eko–titun ni Olumẹgbọn Street. Ekeji ni baba telọ, Jinadu Alade, baba oninure ti o ku ni Iga Kosọkọ ni Ereko; ẹnikẹta ni baba wole-wole atijọ Pa Falaṣẹ ti o jalaisi ni Yaba.

## Tunde Lo

Iku Tunde Joseph dun awọn ẹbi ati ọrẹ rẹ. Arakunrin yi jẹ ọmọ Ologbe Pa Ben Joseph ni Olowogbowo, o si jẹ ẹniti o fẹran ẹbi ati ọrẹ pupọ, idi niyi ti ibi oku rẹ na fi kun ṣọṣọṣọ fun awọn enia jankan jankan ni Ṣọsi ati ni itẹ.

A ki iyawo rẹ, Ọlayinka (ọmọ Plumptre) ati awọn aburo rẹ Fẹmi, Fọlarin ati Abimbọla (aya Glover) pe nwọn ku asẹhinde.

## Oninure

Mo ti nri ẹniti ki binu, ti baba wa telọ (tailor) ti a npe ni Jinadu Alade, ti o jalaisi ni ijesan ọjọ Jimọ jẹ ọkan. Ti ẹ ba si ṣe akiyesi hi oju ọjọ ti ri, ti gbogbo rẹ tutu ninini ẹ o mọ wipe oninure ni baba na, Ko ṣe amodi rara, gbogbo enia ni nwọn rii ni o ku ọla ti yio jalaisi nibi iṣẹ rẹ ni John Street l'Oke-Arin. Gbogbo awọn ọmọ Ijaiye ni o pe sibi oku Ọgbẹni wa na lọkunrin ati lobinrin.

Mo ki awọn ẹbi ọmọ oloku, awọn bi Alhaja iyawo Ajiferukẹ pe nwọn ku asẹhinde. Ọlọrun ki o gbee si afẹfẹ rere.

## Wole–wole

Ọdun metalelọgọrin kiṣe ọmọde ojọ ni ti Pa Falaṣẹ ti o jalaisi laipe yi ni Yaba. Gbogbo ẹsẹ awọn mọriwo ni nwọn kun ibi aisun rẹ ẹniti ko le rin ni ki nwọn gbe on lọ sibẹ.

Mo ti mọ Pa S A Falaṣẹ ti pe nibi iṣe Wole-wole (Sanitary Inspector) nigbati aiye roju. O wa ninu awọn wole-wole ti nwọn bu apa fun mi nigba ajakalẹ arun ni ọdun 1925 ni Eko. Baba yi si jẹ ọkan ninu awọn igi lẹhin ọgba Ṣọsi Methodist Agọ-Ijaiye ni Ebute-Mẹtta. Pa Falaṣẹ, ọrun rẹ o!


**Plushes, Velvet, Velveteen, Damask & Building Materials**

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

63, Massey Srreet Faji Market)

LAGOS, NIGERIA.

The House Where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed.


## Tesan Oko Ofurufu



**Aworan yi ni ti igba ti Olola Bale ilu Edinburgh oko oba ilu Oyinbo fe si ile nla daradara kan ti nwon ko si tesan ibiti oko ofurufu gbe mbale si ni ilu Manchester. Nwon ni irohin ko to afojuba ni ile na.**


Advert. NO. 8.

**Federation Of Nigeria Fourth Development Loan**

The Central Bank of Nigeria has been authorised by the Federal Minister of Finance to raise funds within Nigeria by the issue of £15 Million registered Stock in February, 1963. The Stocks to be issued will be:-

1. £2 Million 5 /o Federation of Nigeria Fourth Development Stock 1968-to be repaid in full on 5th August, 1968.
2. £3 Million 5 1/4o/oFederation of Nigeria Fourth Development Stock 1972-to be repaid in full on 5th August, 1972.
3. £10 Million 5 3/4o/o Federation of Nigeria Fourth Development Stock 1987-to be repaid in full on 5th August, 1987.

The three Stocks will be issued at par in multiples of £10 and applications will be accepted at banks throughout Nigeria or at the offices of the Central Bank in Lagos and Kano up to the close of business on 5th Febuary, 1963.

Prospectuses, which contain full information and application forms may be obtained from banks and Stockbrokers or at the Central Bank's offices in Lagos and Kano up to the close of business on 5th Febuary, 1963.

W. A. TIBBLES,
GENERAL MANAGER.
CENERAL BANK OF NIGERIA.
JANUARY 1963.

# Itan Oba Alake Ademola Keji

## (Lati Owo Omo Abati)

Nigbati mo kọkọ bẹrẹ itan Ọba Ademọla Keji yi ninu ọdun ti o koja, ninu oṣu ti Alaiyeluwa na ṣe ajọdun ọdun mejileiogoji ti o ti gun ori eye, ko ... enini ... mọ wipe ajọdun yi ni yio ṣe igbẹhin ati pe ibi kan ti a npe ni IDI ABA ni Abẹokuta ti mo fi igba kan ... obinrin Ẹgba kan ti o kọ lọ tẹ ibẹ do ni yio je ... Ọba na.

Nigbati e ba nka itan inu iwe yi lọ ẹ o ma gbọ bi diẹ nipa ile ibi kan ni ẹhin-odi ilu Abẹokuta ti a npe ni IDI—ABA ṣe de ọwọ Ọba wa na.

Ariwo Ogun Adubi ni ilu Ẹgba le pupọ ju ti Ogun Ijẹmọ ti awọn ṣoja ti nwọn ni ki nwọn wa dẹruba awọn ara Ijem bẹrẹsi pa wọn lọ, ti Ọba Alake Gbadebọ ọmọ Efunwumi ti o wa lori oye nigba na bẹrẹsi je oriki tuntun bayi "a rẹ Ijẹmobi ni rẹ ia".

Awọn Ẹgba ko fẹ ki nwọn fi ẹlan ti nwọn fi nu awọn ara Ijẹmọ nigba rogbodiyan ti nwọn mu awọn. Nitorina awọn Ẹgba oko ti o da ijangbọn Ogun Adubi yi silẹ nwọn 'o ko o ni ọna kekere; nwọn ke ni ohun ija lowọ bi ti awọn Oyinbo ṣugbọn nwọn fi oju awọn ṣoja ti Ọba Gbadebọ ni ki nwọn fi ṣe iranlọwọ fun on ri mabo.

### Ibon Sakabula

Ibon sakabula ti nwọn fi npa eranko bi ọya, aparo ati awọn ẹiyẹ aganran ti o njẹ wọn ni agbado ati gbaguda ti nwọn gbin soko, ni wọn ni lọwọ gẹgẹbi nkan iṣọra nwọn si fi ibọn na ṣe oṣe pupọ si ara awọn ṣoja na. Eleyi nikan ko ni awọn ṣe, nwọn tun fi ọgbọn miran ba awọn ṣoja na ja. Ona ti awọn Olurogun Ẹgba na lo pọ pupọ ti a ko le ma ka wọn ni ikọkan ninu iwe yi.

Ninu nwọn nja Ogun yi ọwọ ti rogbodiyan nlọ ni arọko, ti awọn ṣoja npa enia bi eni pa ẹranko bẹni awọn ṣoja ti nwọn ko si ni ilu Abẹokuta bẹrẹ si hu pala-pala; nwọn yi okoetile kakiri, nwọn nja nkan ba lọwọ awọn enia ti nwọn ba ri, nwọn si mba awọn obinrin wọn lo pẹlu agbara.

### IDI ABA

Eleyi jẹki inu bi ọkan ninu awọn ọmọ Ẹgba obinrin ti orukọ rẹ njẹ Subuọla ọmọ Ẹgbẹrongbe. Iran Ọba Alake ni obinrin yi; o si jẹ onişowo ti o ni owo lọwọ daradara nigbana. Bi o ti ni owo lọwọ ni o si **ni mọto a**yọkẹ O jẹ ẹnikan ninu awọn Ẹgba ti o kọ kọ ra mọto ni igboro ilu Abẹokuta. O ni mọto - ayọkẹlẹ ti o fi ngba afẹfẹ, o si tun ni eyi ti o fi nko awọn eru ọja rẹ lọ si ọdọ awọn Oyinbo rẹ ni Ibara.

Obinrin yi kii gbe arin ilu ibiti a ngbe ni a npe ni Idi-Aba ni Abẹokuta, o si to irin ibu ọ mefa si arin ilu na. On ni o kọ tẹ ibẹ do ki oto wa di ibugbe fun gbogbo enia nisinsinyi, ọpọlọpọ ile ẹkọ fun awọn ọmọbinrin ati awọn ọmọkunrin ni o wa ni ibẹ.

### Baptist

Awọn ti nwọn kọ kọ ile-ẹkọ sibẹ fun awọn ọmọbinrin ni awọn ọmọ AMERICAN BAPTIST GIRLS' HIGH SCHOOL nwọn si şi ile-ẹkọ na ni nkan bi ọdun mẹtadinlogoji nisisiyi.

Işẹ owo a nra ekuro, epo ati koko (Cocoa) ni Ologbe Subuọla yi nşe titi ti o fi tẹri g'basọ.

Nigbati o ri iwa buruku ti awọn ṣoja yi nhu si awọn ara ilu rẹ, o dide o bẹrẹ si le wọn kiri. Tobẹgẹ ti awọn ṣoja na fi mọ moto rẹ, ti wọn ba gburo rẹ ti o nbọ nwọn a ya sapamọ sinu igbo. Eleyi jẹ ki iwa buruku ti awọn ṣoja na hu dinku diẹ

Arabinrin yi, Subuọla ọmọ Ẹgbẹrongbe, ko duro sibi eyi nikan, o tun lọ si Oyinbo Kọmişanna (Commissioner) ni Oke Igbe o lọ fi ẹjọ awọn ṣoja yi sun nipa iwa buruku ti nwọn nhu si awọn obinrin nilu kakiri. Obinrin yi şe gudugudu meje ninu Ogun Adubi, awọn ọmọ Ẹgba ko si ni gbagbe rẹ ailai gẹgẹbi nwọn ko tile gbagbe IYALODE, gbo gbo Ẹgba, TINUBU ni akoko Ogun Dahọmi.

### Igbalaiye

Gẹgẹbi mo ti fi ye yin ni atilẹwa itan mi wipe Iya afin Subuọla ọmọ Ẹgbẹrongbe ti o lọ tẹ ẹhin-odi ilu ti gbogbo wa wa imọ ni IDI-ABA loni yi do, isẹ owo ni o nşe ti o nra ekuro ati Koko (Cocoa) pẹlu epo nibẹ fun awọn Oyinbo ni Ibara. On ni o si jẹ obinrin kinin ni ilu Abẹokuta ti o kọ ra mọto-ayọkẹlẹ, o si tun ni ikan lọtọ ti o fi nko awọn ọja ti o ba ra lọ si ọdọ awọn Oyinbo ti o mba ra ọja na Ibara.

Ẹyin ara mi, şe ẹnyin na mọ wipe igba ki i lọ bi orere, o to iwọn nkan bi ogoji ọdun nisiyi ni işẹ-owo iya wa na (Subuọla) lọ si silẹ; o si ni wahala diẹ nipa owo Eyi ni o mu ti o fi ta diẹ ninu awọn nkan rẹ ati ile pẹlu ile rẹ ti o tẹdo ti a npe ni Idi-Aba.

Eleyi si jẹ ọkan ninu awọn ẹru arabinrin na ti ọba Ademọla Keji ti sẹsẹ waja yi ra. Ọba yi wa fi bẹ şe ile isinmi ti o ma nlọ sinmi si nigbakugba. Emi alara ti mo nkọ itan yi ti lọ ba Alaiyeluwa Ọba Alake naju nibẹ ni ọpọlọpọ igba nigba aiye rẹ.

Idi—Aba na ni o wa di ibi itan loni fun gbogbo ọmọ Ẹgba nitoripe awọn ọmọ ọba ti diẹ ninu ilẹ ibẹ fun ara ilu lati ma sin awọn Ọba Alake si.

---

## Twin-Engine 'Mini' Beats The Snow



**A new, twin-engined cross-country version of the British Motor Corporation 's fantastically successful Mini car was put through its paces in deep snow recently by Mr.B. McKenzie BMC. Assistant Project Engineer**

**The tiny unorthodox vehicle was fitted with a snowplough for the test and raced through a layer ofsnow two feet deep.**

# ANNOUNCEMENT.

## NIGERIAN PORTS AUTHORITY
KANO OFFICE

THE NIGERIAN PORTS AUTHORITY has pleasure to announce that its KANO OFFICE has been opened for business in the building of the Northern Region Marketing Board, Post Office Road, Kano-Telephone Number: KANO 2269.

The Authority's Northern Representative (MALLAM ABDULLAHI OBADAKI), permanently domiciled in Kano will welcome and deal with questions pertaining to the handling of cargo at ports, and with dues, rates and charges and any difficulties that may be experienced by customers of the Authority.

N. P. A. Notice No. 855
26th January, 1963.

BAYO KEHINDE
Secretary to the Authority.


# QUEEN AND PRINCE Philip On Tour

LONDON — The Queen and Prince Philip, left London on Thursday by air for their 30,000 mile tour of Fiji, Australia and New Zealand.

Having arrived at Nadi International Airport, Fiji, on Friday, they travelled in the Royal yacht 'Britannia' to Suva where an elaborate Fijian welcoming ceremony in the yacht has been planned.

They are due to arrive at Waitangi, New Zealand on 6th February. After visiting cities and towns in both islands they will leave for Canberra, Australia, on 17th February.


**Read an Advertise In Eleti-Ofe**


## British Overseas Information Services To Be Increased

LONDON - Britain is to spend an extra £1,000,000 a year largely on helping the British Council's English teaching and training work.

This was stated in the House of Commons yesterday by the Secretary for Technical Cooperation, Mr. Dennis Vosper who added that he would consider sending British journalists overseas to help newspapermen in developing countries if such a request was made by an overseas government or governments.

## New British Deputy High Commissioner For Kaduna

The new British Deputy High Commissioner in Kaduna, Mr. William Stanley Bates arrived in Lagos on the m.v. "Apapa" yesterday. On Monday he will fly to Kaduna to take up his appointment in succession to Mr. H.A. Twist, O.B.E.

Born on 7th September 1920, he was educated at Christ's Hospital and Corpus Christi College, Cambridge.

He joined the Commonwealth Relations Office in 1956, and served for three years in Canberra Australia.

## Ghanaian Ordained In London

LONDON — A Ghanaian Mr. George Oko Jomoa, from Eso, has been ordained and inducted as an Elder of the Oxendon Presbyterian Church in Haverstock Hill, London.

Mr. Jomoa has been studying transport management at the City of London College for the past year.




CARSON'S PAINTS AND VARNISHES




SOLE AGENT—

IKORODU TRADING COMPANY

# Olotu Tubman Fe Ran Awon Omo Olympio Lowo

LIBERIA— Bole ilu Liberia, Ọlọla Tubman ni irohin kan wa lati ilu rewa wipe o ti kowe si awọn ọmọ-ẹbi Dokita Sylvanus Olympio, alakoso ilu Togo ti awọn Ọlọtẹ pa ni ipatọn laipe yi wipe ki nwọn fi meji ninu awọn ọmọ rẹ ranṣẹ si ilu on ki on wo nkan ti ijọba ilu on le ṣe fun wọn.

Ọlọla Tubman ni on ti gbọ gbogbo ipinnu ti awọn ogun-gbogbo orile ede ijọba ilu Afirika ṣe lati ran awọn ọmọ Ologbe Olympio lọwọ ninu apejọ nla ti nwọn ṣe ni ilu Nigeria ni ọsẹ yi.

## E ma ka iwe irohin Eleti—Ofe ki e si ma polowo oja yin losose.

Never

refuse a trial run before you choose a car. Let the cars speak for themselves and be scrupulously critical when looking at different models. We are convinced (from long experience) that any Mercedes-Benz will pass such an examination with top marks. Please give us the opportunity of substantiating our claim.

MERCEDES-BENZ

LEVENTIS MOTORS LTD.

Lagos . Ibadan . Kano . Kaduna . Jos . Port-Harcourt . Aba

Sub Distributors:

ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN CITY . ONITSHA . ABA



# Irohin Soki

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Ọla C.D. Akran tiṣe minisita alamojuto eto owo Ijọba tuntun Ipinlẹ Iwọ Orun ti Ijọba Ipinlẹ na yan ni aṣoju wa si ipade na ni "IGBA BAARA" ni on gbe wa si ipade ajọ na nitori gbogbo owo ni awọn ti na tan ni Ibadan, ko si owo lọwọ Ijọba awọn mọ.

Emkan ti ji i sọ fun mi wipe Oloye Festus Okotie-Eboh, minisita alamojuto eto owo Ijọba apapọṣe pẹlu awọn ẹlẹgbẹ rẹ ti bẹrẹsi f'ori kan ori ni Ikoyi lati ro eyiti awọn yio ṣe gẹgẹbi iranlọwọ fun "awọn ọrẹ wa, ko tilẹ yẹ, ko si tọ ki awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ tẹ ninu Ijọba ti nwọn ṣẹṣẹ mba wọn ṣe ni Ibadan yi".

Lẹhin ipade na Oloye Okotie-Ẹbọ pẹlu iyawo rẹ fi nkan adidun tọ awọn Minisita ti o wa si ipade na lenu wo ninu ile rẹ, o'tun ṣe ileri fun Ọbn Akran pe laipe yi awọn yio da oporo owo bo wọn ni Ibadan, ṣugbọn nibiti owo na ti mbọ ni ko ye emi Ayiluka si; boya ninu eyiti awọn alanu nya wa lati ilu ajoji na ni. Ọrọ re o;

## Ilu Egba

Lati iwọn nkan bi oṣu kan ni gbogbo agbaiye ti ntẹ eti silẹ lati mo gbọ gbogbo bi nkan ti nlọ si i Abẹokuta ilu awọn Ẹgba ẹlu awọn meji ti nwọn ti hinti Ọba Ladapọ Ademọla Keji ti waja. rohin ti mo tun gbọ nigbati mo de ilu Abẹokuta na ni wipe awọn Ologboni ti tun yan Oloye Adegunlẹ Ṣoṭan (lọya mi atijọ) lati an ni "Adele" Alake si Afin l'Ake.

## Eru Alake

Onirohin mi ni ojoju 1ọ ni awọn "Adele" na pẹlu awọn ologboni afọbajẹ nri iwe gba lati ọwọ awọn ti o nsọ wipe Oyekan awọn; mo si gbọ wipe Oyekan awọn mo si gbọ wipe nwọn ko tilẹ ti ya si ọrọ awọn ọmọ ọba na rara nwọn ni nkan ti o ku lẹhin mẹfa ju meje lọ.

Gbogbo ẹru ti ọba ti o waja na fi silẹ ni nwọn si nyanju lọwọ na ni ikọkan. Awọn adegolu wa nibẹ, ọpa ilẹkẹ wa nibẹ pẹlu bata ilẹkẹ bẹni ẹwu ilẹkẹ oriṣiriṣi ti a le pamọ si ile iṣura Ẹgba (Ẹgba Musem ti awọn ọmọ wa le ma ri wo ki nwọn si ma niran aiye Ọba Ademọla lẹhinọla. Ẹ jọwọ ẹnyin ologboni, ẹ ba wa ṣe eto na ko dara o !

## Owo Lebira

Mo gbọ irohin wipe ipada ti gbogbo awọn Minisita alamojuto eto a-nfi-ni-siṣẹ ṣe l'Eko ni ọsẹ yi dun pupọ, gbogbo Ipinlẹ Ijọba patapata lo pesẹ sibẹ, Oloye Adiun lati Ibadan, Ọgbẹni Akpabio lati Enugu, Alhaji Ahmadu lati Kaduna pẹlu Oloye Modupẹ Johnson ti gbogbo nwọn wa ba l'Eko.

Mo gbọ wipe nwọn ti ṣe ipinnu pataki kan lati ṣe ofin ki gbogbo awọn ọga ile iṣẹ ma san owo loṣọṣẹ tabi nijọ mẹdogun mẹdogun fun gbogbo awọn oṣiṣẹ bi nwọn ti nṣe ni ilu Oyinbo ati ni Amẹrika; boya eleyi le din ko s'owo ko s'owo ku lọdọ awọn oṣiṣẹ.

## Olosa Kan Gbe Sende Je Nigbati O Ri O Ri Olopa

APAPA — Onimọto Takisi kan, John Ogbeke ti awọn ọlọpa Apapa ti mọ'le lori sefu (save) nla kan ti nwọn ẹ fọ lati ji owo ko nibẹ ni a gbọ wipe o gbe sẹndẹ jẹ o si ku sinu ile ihamọ na loru ana. Owo ti nwọn fẹ fi san owo oṣu awọn oṣiṣẹ NIGERIAN PORTS AUTHORITY ni awọn ọlọsa na fẹ JI GBE nibiti nwọn ko wọn pamọ si.

Nigbati ọlọpa lọ yẹ ile Ogbeke wo nibiti o gbe ngbe nwọn ba agolo sendẹ ti nwọn fi npa ekute nibiti o nibiti o gbe asun pẹlu diẹ toku ninu iyara rẹ.

Printed and Published by The Union Printing & Publishing Company 28, Kosọkọ St., Phone 23370 Lagos
Editor (Oloye) Ọla Ọnabade, 18, Kosọkọ Street, Lagos.